# ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU

Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.

**Oṣù Kẹta, Ọdún 2025**

**Agbára Gbọ́dọ̀ Pàrọ̀ Ọwọ́**

## AGBÁRA GBỌDỌ̀ PÀRỌ̀ ỌWỌ́ OṢÙ KẸTA, ỌDÚN 2025

1. **Ha ẹgbẹ́ mi ẹ w'àsíá!**
   Bó ti nfẹ́ lẹ́lẹ́!
   Ogun Jésù fẹ́rẹ̀ dé ná,
   A fẹ́rẹ̀ ṣẹ́gun.

   "D'odi mú, Èmi fẹ́rẹ̀ dé"
   Bẹ́nì Jésù wí,
   Rán 'dáhùn s'Ọ́run pé,
   "Àwa o dí mú".

2. Wo ọ̀pọ̀ ogun tí mbọ̀ wá;
   Èṣù nkó wọn bọ̀;
   Àwọn alágbára n ṣubú,
   A fẹ́ dàmú tán!

3. Wo àsíá Jésù tí nfẹ́,
   Gbọ́ ohùn ìpè;
   A ó ṣẹ́gun gbogbo ọ̀tá,
   Ní orúkọ Rẹ̀.

4. Ogun ngbóná girigiri,
   Ìrànwọ́ wa mbọ̀;
   Balógun wa mbọ̀ wá tete,
   Ẹgbẹ́, tújúka!

1. **Ẹ̀nyin olùkórè nín'oko**

T'árẹ̀ fẹ́rẹ̀ mú tán
Ẹ rọ́jú dúró de Olúwa
Y'Ó s'agbára dọ̀tun

Àwọn tó dúró d'Olúwa
Y'ó s'agbára wọn d'ọ̀tun
Nwọn ó fi ìyẹ́ fò
Nwọn ó fi ìyẹ́ fò bí ìdì
Nwọn ó sáré, nwọn kì y'ó k'árẹ̀
Nwọn ó rìn, kì ó rẹ̀ wọ́n
Nwọn ó sáré, nwọn kì y'ó k'árẹ̀
Nwọn ó rìn, kì ó rẹ̀ wọ́n
Nwọn ó sáré, nwọn kì y'ó k'árẹ̀
Nwọn ó rìn, kì ó rẹ̀ wọ́n

2. Nígbà àrẹ́ àt'irẹ̀wẹ̀sí

À ngb'ọkàn wa sí Ọ
Lẹ́yìn t'agba Olùgbàlá gbọ́
Kí l'a ó tún bẹ̀rù?

3. Ẹ yọ̀! Ó mbá wa gbé lọ́jọjọ́

Àní títí d'ópin
Wòkè! ẹ sì ma tẹ̀sìwájú
Y'ó fùn nyín l'ágbára.

## **ỌRỌ̀ AGBÁRA**

1. Àwọn agbára òkùnkùn tí wọ́n gbẹ́kẹ̀lé ìwà ìkà láti gbóguntì ayé mi, ejò atòkèwá láti ọ̀run yóò gbé yin mín lónìí, ní orúkọ Jésù.
2. Àwọn agbára ìkà tí wọ́n kórajọpọ̀ lòdì sí ìpele mi t'ókàn; àrá Ọlọ́run yóò pa yín run lónìí, ní orúkọ Jésù.
3. Gbogbo rìkísí ibi ilé bàbá mi tó lòdì sí ìpele mi t'ókàn, túká nípa iná, ní orúkọ Jésù.
4. Agbárakágbára òkùnkùn tó wí pé n kò ní jẹ èso làálàá mi, ìwọ kọ́ ni ẹlẹ́da mi, kú, ní orúkọ Jésù.
5. Àwọn agbára tí wọ́n n ṣiṣẹ́ òkùnkùn láti dá ìràwọ̀ mi dúró kí ó máṣe tàn, ẹ gbọ́ Ọ̀rọ̀ Olúwa, ìbínú Ọlọ́run yóò pa yín run lónìí, ní orúkọ Jésù.
6. Gbogbo agbára àjèjì tí wọ́n ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ ìdánilójú lòdì sí ayànmọ́ mi yóò gba ìparun lónìí, ní orúkọ Jésù.
7. Àwọn agbára tí wọ́n nrìn jìnà láti ri pé mo sọkún, ẹ gba ọfà ikú, ní orúkọ Jésù.

## **ÀDÚRÀ ÀDÁGBÀ**

**ÌJẸ́WỌ́ - ORIN DÁFÍDÌ 91**

1. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn sí Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìsọjí bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Ẹnu ìkà tó nfa ètò-ìṣúná mi mu, gb'iná, ní orúkọ Jésù.
4. Àwọn agbára tó nlo atẹ̀yìnwá mi láti gbóguntì mí, gba ìdahoro, ní orúkọ Jésù.
5. Àwọn agbára tí wọ́n wí pé n kò ní de Ilẹ Ileri mi, ya wèrè, kí o sì kú, ní orúkọ Jésù.

6. Agbárakágbára tó n ṣàbẹ̀wò sí àwọn ibi ìpàdé òkùnkùn pẹ̀lú orúkọ mi, wólulẹ̀, kí o sì kú bayii, ní orúkọ Jésù.
7. Gbogbo ágbara ìkà, tó dúró sáàrín èmi àti àwọn ibùkún mi, kú, ní orúkọ Jésù.

## ÀDÓ Ọ̀RỌ̀ NÁÀ

**Ìsáíàh 40:29-31:** Ó nfi agbára fún alárẹ̀; Ó sì fi agbára kún àwọn tí kò ní ipá. Àní arẹ́ yóò mú àwọn ọ̀dọ́mọdé, yóò sì rẹ̀ wọ́n, àti àwọn ọ̀dọ́mọkùnrin yóò tilẹ̀ ṣubú pátápátá. Ṣùgbọ́n àwọn tí ó bá dúró de Olúwa yóò tún agbára wọn ṣe; nwọn ó fi ìyẹ́ gun òkè bí idì; nwọn ó sáré, kì yóò sì rẹ̀ wọ́n; nwọn ó rìn, arẹ̀ kì yóò sì mú wọn.

**Ìsáíàh 57:18-19:** Mo ti rí ọ̀nà rẹ̀, èmi ó sì mú u lí ara dá: èmi ó sì tọ́ ọ pẹ̀lú, èmi ó sì mú ìtùnú padà fún u wá, àti fún àwọn aṣọfọ̀ rẹ̀. Èmi li ó dá èso ètè; Àláfíà, àláfíà fún ẹnití ó jìnà réré, àti fún ẹnití ó wà nítòsí, ní Olúwa wí; èmi ó sì mú u lí ara dá.

**Ìsáíàh 58:8:** Nígbàná ni ìmọ́lẹ̀ rẹ yóò bẹ́ jáde bí òwúrọ̀, ìlera rẹ yóò sọ jáde kánkán: òdodo rẹ yóò sì lọ ṣájú rẹ; ògo Olúwa yóò kó ọ jọ.

**Isàíàh 53:4-5:** Lótọ̀, Ó ti ru ìbìnújẹ́ wa, Ó sì gbé ìkánú wa lọ; ṣùgbọ́n àwa kà á sí bí ẹnití a nà, tí a lù láti ọ̀dọ̀ Ọlọ́run, tí a sì pọn lójú. Ṣùgbọ́n a ṣa a lí ọgbẹ́ nítorí ìrékọjá wa, a pá á lí ara nítorí aìṣedédé wa; inà alàfíà wá wà lára rẹ̀, àti nípa inà rẹ̀ li a fi mú wa lára dá.

**Isàíàh 41:13:** Nítorí èmi Olúwa Ọlọ́run rẹ yóò di ọwọ́ ọ̀tún rẹ mú, èmi ó wì fún ọ pé, Má bẹ̀rù; èmi ó ràn ọ́ lọ́wọ́.

**Isàíàh 33:2:** Olúwa, ṣànú fún wa; àwa ti dúró dè Ọ́: Ìwọ ma ṣe apá wọn lí oròwúrọ̀, àní ìgbàlà wa nígbà ìpọ́njú.